

# Gbádùn kíkùn nnkan àti yíyà àwòrán

Kíkùn nnkan àti yíyà àwòrán nran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti mú kí ìfojúsílẹ̀, ojú ọnà, àti àwọn ìmọ̀ tí yóò nílò fún ìwé kíkọ rẹ̀ dàgbà sókè.

Lo onírúurú ohun èlò tí a fi nsàmì sí ara nnkan—kereyọọnu, lẹẹdi ìkọ̀wé, nnkan ìfárungbọn tí ó le àti ọ̀dà. Ó jẹ́ ohun ìgbádùn láti lo omi àti irin iṣẹ́ tí a fi nkun nnkan lórí òkúta tí a tẹ́ sílẹ̀.

**Olobó oníràwọ̀**
Ní ojú ọnà. Ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ láti sàmì, ya àwòrán kí o sì fi ọ̀pá ya àwọn àwòrán tí a fi onírúurú nnkan bí ìyẹ́, ìkarahun tàbí ọ̀mùnú-igi.

Gé àwọn ààyò àwòrán láti inú àwọn ìwé àtìgbàdégbà kí ó sì ṣe àwọn àwòrán aláṣàpọ̀.

### Bí o ti lè ṣe ìwé ìránnilétí tìrẹ

Ohun tí o nílò

- Ìwé tí a nlẹ̀ àwọn àwòrán mọ́
- Àwọn pẹẹni, kereyọọnu àti lẹẹdi ìkọ̀wé
- Àwọn fọ́tò
- Àwọn ìwé-ìròyìn àtìgbàdégbà àti ìwé àwòrán ọjà
- Sisọọsi ọmọdé tí kò léwu
- Gúluù

Ohun tí o maa ṣe

- Ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti ṣe iwájú ìwé ìránnilétí rẹ̀ lọ́ṣọ̀ọ́. Ẹ jọ kọ orúkọ wọn síi.
- Fikún àwọn ọ̀rọ̀ tàbí àwòrán nípa ohun tí wọn yàn láàyò, bí ounjẹ, àwọn ibikan tàbí ohun ìṣeré, tàbí àwọn foto ìdílé rẹ tàbí àwọn ohun ọ̀sìn rẹ.
- Gba tikẹẹti ọkọ̀ àti àwọn míràn nígbà tí bá jáde kí o sì jẹ́ kí ọmọ rẹ lẹ̀ wọ́n mọ́lẹ̀.
- Gbìyànjú láti jẹ́ kí ọmọ rẹ lọ ohun tí ó ndán, ọ̀dà, àlẹ̀mọ̀ tàbí ohunkóhun láti mú kí ìwé ìrántí rẹ̀ wuni kí ó sì ní onírúurú àwọ̀.

**Lọ́rọ̀ kúkurú**
Sọ̀rọ̀ nípa àwọn ohun tí ọmọ rẹ fi ọwọ́ yà kí o sì béèrè ohun tí ó ti yà. Ṣa àwọn ìrí àti àwòrán tí a lè dámọ̀ kí o sì fúnra rẹ ya àwọn kan.

